ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 881 LAGOS SATURDAY AUGUST 10 - AUGUST 16 KOBO MEJI (2D) 1963

UNIV. IBADAN LIBRARY

Agan Fe Be!

# Awon Olojo Eko, Ibadan Ati Shaki Fe Danrawo

## Awon Jaguda Eko

EKO—Orişirişi aşa ti a ko ti gbọ ri ni o nyọju nisis yi, eyiti a tun gbọ loru ana ni ti awọn onişegun afoj ti ilu Eko, Ibadan ati ti Shaki ti nwọn nleri leti şe atako ẹra wọn pe ẹnikan lo ni agbara ju lati fa ojo tabi lati ti ojo wipe ki o ma rọ rara ni oni Satide ni ilu Ibadan ti nwọn fẹ şe ere a nja ẹşẹ larin awọn ọmọ ilẹ wa, Dick Tiger ati Oyinbo alawọ funfun kan ti nwọn npe ni Gene Fullmer.

Ogunlọgọ enia ni nwọn ti ra iwe afiwọle (ticket) lati lọ wo iran na loni. A gbọ wipe Oloye J M Johnson pẹlu Oyinbo kan lọ si Ijọra ni ana lati lọ bẹ baba afajo ti o wa nibẹ wipe ki o gba awọn ki o ma jẹki ojo rọ rara nitoripe ẹtẹ awo ni ẹtẹ ọgbẹri.

Awọn ara Ibadan paapa ti ti ranşẹ si awọn ọdẹ ara Shaki wipe ki awọn na şa agbara ti wọn loni.

# Awon Bale Meji Nja Lori Omo Ikoko Kan

EKO — Şangba fọ ninu ile ibi işẹ awọn oniwe ọjọbi ọmọ tuntun ni ijẹta nigbati awọn ọkunrin meji nja lori ọmọ tuntun kan wipe awọn ni awọn daşẹ rẹ ki iya rẹ to gboyun rẹ fọkọ miran ni Ẹpẹtẹdo.

Suratu Abikẹ ti o ngbe Freeman Street ni Oke Popo ni a gbọ wipe on ni o bi ọmọ ikoko na ti awọn ọkunrin meji nja lelori yi.

Onirohin wa ti ọrọ na soju rẹ ni ọkọ akọkọ ti orukọ rẹ njẹ Mutiu Alimi ti o wa l'Oke Suna ni o kọ wa sọ fun awọn akọwe oniwe ọjọbi wipe iyawo on bi ọmọ tuntun kan, on si sọmọ na ni Fatai Oluşẹgun ati pe on fẹ ki nwọn fun on niwe ọjọbi ọmọ na.

(We iyoku loju ewe keji)

## Sede Ni Ibadan



**Oba Adele Keji** na nlọ woran ija ẹşẹ na.

### Awon Jaguda

A tun gbọ wipe gbogbo awọn jaguda pali ilu Eko ti wọ mọto lọ ba awọn ara wọn ti nwọn wa ni ilu Ibadan pe ijẹ de fun awọn. Awọn ni lati ri owo şe ninu gbogbo eyiti o delẹ yi.

Awọn ole ti yio gbe mọto ati awọn ti yio ma tọwọ bọ wọn lapo ti mura silẹ jaburata, şugbọn ju gbogbo rẹ lọ awọn Ijọba ti k o ọpọlọpọ awọn ọlọpa ati sọja lọ si Ibadan fun ti ere ẹşẹ ti oni.

## Malu Ja Ludo Adamalu Ku Si Salanga

APAPA—Onikoko pelu kokorẹ ti wọn jọ ma gbe, gbolohun yi ni ti ọdọmọde Hausa kan ti o ku si inu salanga ni Apapa Ajegunlẹ, nibiti o gbe nda malu lọ. Adamalu yi ri ọkan ninu awọn malu rẹ ti o nsare lọ sinu adagun omi kan ti ọsọrọ ojo ti da silẹ ni ẹgbẹ kota, bi o ti nsare lọ da malu yi pada ki o maba ja si Şalanga ni on na paapa wa jin si koto. Malu yẹ, Adamalu ku patapata.

## Ayilara Thompson Jalaisi Ni Idita

EKO—Gbogbo awọn gbajumọ ara Eko lọkunrin ati lobinrin ni nwọn pe siba si ibi isinku oku Ọgbẹni Yesufu Amudani Ayilara Thompson ti o jalaisi ni ijẹta ni agbole Thompson ni Itọlọ. Lẹmọmu gbogbo ilu Eko, Alufa Liadi, ni o şe asiwaju eto isinku na ni ile ati ni itẹ ni Okesuna.

Lẹhinti oku yi ti wọlẹ tan ni awọn ọmọlọku ati awọn ẹbi wọn wa bẹrẹsi ha owo fun gbogbo awọn enia ti nwọn wa ki wọn, bi nwọn ti nha owo bẹni nwọn tun fi nkan jijẹ ati mimu tẹ wọn lọrun.

Ninu awọn ọmọ ti Ologbe na fi silẹ ni Ọgbẹni Danialu, Alhaji Mustapha, Raolatu Iyawo Ọgbẹni Idewu, Adamu, Amudalatu, Kayọde ati Abasi.

Ologbe Amuda Thompson jẹ gbajumọ pataki nigba aiyẹ rẹ, işẹ owo ni o si nşe.

A ki awọn ẹbi Thompson lọkunrin ati lobinrin wọn ku aşẹh nde, ẹhin oku na a si dara.

## Awon Bale Meji Nja Lori Omo Ikoko Kan

(O bẹr; loju ewe kinni)

Bi ọkunrin yi ti nsọ eyi lẹwọ, ti awọn akọwe oniwe ọjọbi si nkọ ọrọ rẹ silẹ ni ọkọ keji Saratu fẹ lọsan wọle de lati Ebute-Mẹtta, Lasis Adekule ni orukọ rẹ njẹ; o ni on ni iya ọmọ na bi ọmọ ikoko ti Alimi nfẹ gbawe ọjọbi rẹ yi fun.

Akọwe-agba ile-iṣẹ ibiti nwọn ti ngba iwe ọjọbi ọmọ ni ọrọ na ko ye on ki nwọn sọ ki o ye on daradara. Agan fẹrẹ bẹ nibiti olukuluku wọn gbe ti nṣe alaye ọrọ tirẹ.

Alimi ni on ni ọkọ Suratu, ni ọdọ awọn ẹbi rẹ ni on ti fẹ ni Oko Abe l'Ẹpẹ, on si san owo iyagbọ ati baba-gbọ lori rẹ ki nwọn to faa fun on ni iwọn nkan ọdun kẹsan sẹhin.

Alimi ọkọ arọ yi ni iyawo on na loyun kan fun on o si fi bọmọbinrin ṣugbọn ọmọ na ti jalaisi Oyun keji ti iyawo on na ni o gbe jade nile on nigbati awọn ṣẹ gbolohun asọ kan o ni oyun na ni o fi bi ọmọ yi.

Adekunle, ọkọ keji ni ọrọ ti on ko pọ, o ni iyawo ọlẹ ni a gba a ki gbọmọ rẹ. O tun ṣe jalaye siwaju wipe bi Alimi ba ni nṣe Suratu ba wa lẹnu on, o le ma mu iyawo rẹ lọ, ṣugbọn ni ti ọmọ ikoko ti obinrin na bi yi, On ni on fun loyun rẹ, on ni on yio si ko ọmọ na jade.

## Alamojuto Iwadi Ipinle Agbedemeji Jalaisi

Benin-City—A gbọ ju igba silẹ ni awọn ara ilu Binin gbọ iku Oloye Gabriel Longẹ, ẹniti o ṣe alamojuto eto idibo fun Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun laipẹ yi, ti o to sanlẹ ti o si ku lojiji bi o ti nwọ ilẹ rẹ lọ ni ijẹrin.

Ẹni ọdun mọkandilọgọta ni ologbe na, o si lọ si ilewe giga St Andrew ni Ọyọ lẹhinti o jade ilewe o ṣe iṣẹ tiṣa olukọni titi ki o to lọ si ilu Oyinbo lọ kọ iṣẹ lọya agbẹjọro.

Ọmọ Sabogida Ọra ni igberiko Binin ni ologbe Longẹ, o si fi iyawo ati awọn silẹ. Ni ijẹta ni nwọn sinku rẹ ni Ṣọṣi kan ni ilu rẹ.

# Kora F'owo Tanran Nitori Pulu

IBADAN — Oyinbo Kọra kan ti orukọ rẹ njẹ John Chidiak ti awọn ọlọpa ti mba ṣe ẹjọ wipe o nṣe iṣẹ pulu (poolss) lai gba iwe aṣẹ ni a gbọ wipe adajọ kan ṣa konko mọ lori ni ijẹ a wipe ki o lọ san pọnun marundinlogoji tabi ki lọ ṣẹwọn oṣu meji.

Awọn ni awọn ti nṣe ikilọ fun awọn ti o nfi iṣẹ bọlu afẹsẹ gba si jẹun ti pẹ wipe ki nwọn tete lọ gba iwe-aṣẹ nitoripe ofin iṣẹ pulu ti le nisisiyi.

'Awọn ọlọpa tun ṣe ileri fun adajọ na wipe gbogbo awọn oniṣe pulu ti nwọn nṣe wayo ni awọn a gbe ni janto wa si iwaju adajọ nibikibi ti nwọn ba wa.

TAFAWA JẸWỌ ỌRỌ BURUKU:

## On Ni O Damoran Ofin Eleha

EKO—Ọlọla Tafawa Balewa, alako Ijọba Apapo ilẹ Nigeria jẹwọ ọrọ buruku fun awọn ti o pejọ sinu ile igbimọ aṣofin ni ijẹta, o ni on ni on damọran wipe ki awọn ṣe ofin ẹlẹha kan ti awọn yio ma fi de awọn ọta Ijọba mọlẹ lai jẹ wipe awọn ko wọn lọ si ile ẹjọ lati sọ tẹnu wọn.

Ọlọla Balewa ni nigbati on ri wipe ofin eto ilu awọn ko faye silẹ lati mọ nkan ti awọn le ṣe fun awọn janduku enia ti nwọn nfẹ gbegun ti Ijọba. O ni eleyi ni o jẹki on fi ọrọ na siwaju awọn alakoso Ijọba yoku nigbati wọn wa si Jos.

Lọya L J Dosunmu, ọmọ ẹgbẹ AG fẹnu kan ofin tun tun ti ile igbimọ na fẹ ṣe lati le mọ ge awọn Kansilọ Eko lọwọ ninu ile igbimọ wọn. O ni ọrọ na ko ba oju mu rara.

Ọgbẹni Dosunmọ ni o yẹ ki nwọn ju ọrọ ile igbimọ ibilẹ Eko silẹ ki nwọn ma jiroro bi nwọn ti nṣe nkan wọn lati ilẹ wa.



# Iya Oba Goke Agba

Aworan ti e nwo yi ni ti iya ti o bi obabirin ilu Gesi ti o wa lori ite nisisiyi, Elizabeth ni oruko ti on na nje. Ni ojo ti o nse ojobi arare ni o gba aworan yi ninu ile ti o ngbe. O di eni odun metalelogota nisisiyi. Enyin na ko ri bi awo ara re ti tutu nini.

# Alaye Eto Ilera Ti Ijoba Fe Gbe Jade Fara Eko (3)

Gęgębi a ti se ileri fun ęnyin ọ̀kawe nigbati a şęşę bęrẹsi tẹ alaye eto ilera ti Ijọba apapọse ilę Nigeria fę gbe jade fun Eko wipe fun ọdun gbọrọ ni eto ile aisan kakiri ilu Eko o ti d ra, ati pe eyi ni o jẹki ijọba yan Oyinbo dokitak Halevi olokiki kan wipe ki o wa ba awọn yẹ işẹ ọwọ awọn lori ile iwosan (hospital) ti awọn ni igboro Eko ki awọn le mọ nkan ti awọn le şe si.

## Nibiti A Ba Oro Na De

Lati bi ọsẹ meji ti a ti mba ọrọ na bọ ninu iwe irohin yi, a ti sọ fun yin wipe ijọba ni owo nla ni eto ilera na ijoba ati awọn ara ilu Eko, alaye yi ni o mu awọn oşşẹ ti o wa l'Eko fọnmu, ki nwọn faake kọri wipe awọn ko fẹ nkan yio tun ko awọn si gbese asausantan. Ẹnyin na si ti ka nkan ti awọn ọmọ egbẹ dokita onişegun ti nwọn nda işẹ se fun ara wọn (Nigerian Medical Association) şe nipa eto ilera na ati bi nwọn ti kọ lati faramọọ.

Gbogbo eyi ko di awa Eleti-Ọfẹ lọwọ lati tẹ gbogbo iwe alaye ti Ijọba tẹ jade lori ọrọ na. Bi o ko ba le ka a tan loni fi nwọn silẹ fun awọn ọmọ ti o mbọ lọla, ki nwọn le mọ iru idan ti a pa fun wọn, boya idan rere ni tabi idan buruku. O ya, ẹ ma ka a niso:

## Osise Tuntun

Nigbati a ba pari eto işẹ ilera ati itọju awọn alaisan mọkanla na tan, ti a si nlo wọn dada, Ijọba ni awọn ti şe eto lati gba awọn dokita mẹrinlelogoji kun awọn ti o ti wa nilẹ pẹlu awọn oşişẹ jaburata ni orişirişi, o bẹrẹ lọdọ awọn nọsi titi ti o fi de ọdọ awọn dẹrẹba ti yio ma wa mọto ti nwọn yio ma fi gbe awọn alaisan. Bakanna, ọpọlọpọ stet ibẹwo ni awon oşişẹ ma yio ma şe si ọdọ awọn alailera ninu ile wọn.

Niwọn igbati o ti jẹ wipe tọsan-toru ni awọn ile itọju alaisan titun na yio fi ma şşẹ, idaniloju wa pe ko ni si ọpọlọpọ awọn enia ti yio ma to siwaju awọn ile-iwosan ati ile egbogi Ijọba mọ ni ilu Eko. Awọn alasan yio si le gba itọju ki aisan to wọ wọn lara. Eyi yio din inawo wọn lori itọju ku; bakana, yio si din ewu si ẹmi wọn nitori aisan ku.

## Awon Abiyamo

Itọju pataki wa fun awọn abiyamọ ati ọmọ kekere ni abẹ eto işẹ ilera titun yi. Awọn abileko ko ni ma fi gbogbo ọjọ fi işẹ wọn silẹ lọ to siwaju ile iwosan lati ba le ri 'dokita.' Ni abẹ lai pa işẹ wọn miran lara.

Nipa awọn ọmọ kekere ti ara wọn ko da, eto titun yi fi aye silẹ pe ki nwọn fun wọn ni itọju kiakia, lai fi akoko şofo. Eto na tun fi aye silẹ fun ayẹwo awọn ọmọde lati igba de igba, ki a ba le tete mọ awọn ti ara wọn ko da, ati lati fun awọn wọnyi ni ogun ti yio fun wọn ni abo ki arun ma le kọlu wọn.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# Awon Danadana Gbowo Lowo Oyinbo Onisowo Kan

SAPẸLẸ — Awọn ọlọşa danadana kan ni a gbọ wipe nwọn da Oyinbo onişowo kan ti oruko rẹ njẹ Ọgb de Groot lọna nigbati o nlọ si Ibadan lati Sapelẹ nwọn si ja owo iyebiye gba lọwọ rẹ ni ọgangan ibiti awọn kan ti ja ọke meta ponun (£60,000) gba lọwọ awọn akọwe banki lẹşin.

Awọn Ọlọpanu ti o wa bi Ibadan ni igberiko kan ti nwọn npe ni Koko ni o fẹ gbe owo na lọ lati fi san owo fun awọn enia kan. Nwọn ni bi moto ayọkẹlẹ rẹ ti de ibiti nwọn gbe gba owo lọwọ rẹ, igi gedu kan ni o se akiyesi wipe awọn kan sọju ọna.

Oyinbo yi si da mọto rẹ duro lati wo bawo ni on şe le kọja, wara were awọn enia kan ti nwọn kan ti nwọn sapamọ sinu sinu igbo sare jade nwọn yinbọn si mọto ẹ, nibiti Oyinbo yi gbe ngbọn pẹlu ẹru, ni nwọn ba ja apo owo gba lọwọ rọ ninu moto.

Wara were awọn ọlọşa na ti tun bẹ sinu igbo, nwọn ti ba ti wọn lọ

## Awon Egbe Serafu Se Ipade Ajodun

IBADAN—Irohin ko to afojubatni ajọdun gbogbogbo ti awọn ọmọ ẹgbẹ Serafu ati Kerubu şe lọjọ ọsẹ ijeje ni ilu Ibadan, orişirişi awọn enia ẹka ẹgbẹ na ti o wa ni Eko, Abẹokuta, Ọyọ, Ilesha, Ile Ifẹ, Ogbomọsho, Ekiti ati awọn ibomiran ni nwọn wa si ibi isin ipade.

Nwọn bẹrẹ isin ipade na ni ile isin awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn ko si Oke-Seni leti Idikan, olukuluku wọn si wọ aşọ funfun.

Lẹhin eyi nwọn to lẹwọlọwọ gba Oke Mapo lọ, bi nwọn ti nlọ ni nwọn nkọrin iyin ati ogo s'Ọlọrun Odumare fun ayọ ti o da wọn si dọjọ na

Nigbati nwọn de Oke Mapo, Ẹni ọwọ Woli J. Akande lati Ogbomọshọ ni o şe iwasu akanşe lọjọ na, o si sọ pato ọrọ. Ẹyẹ ọjọ na yẹ wọn pupọ.

# Eleti–Ofe D'araba

# ELETI–OFE

(A NJU WỌN KOSE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 881SATURDAY AUG 10 – AUGUST 16 1963


## Oro Olotu :

# Awon Ara Eko Ju Nkan Atata Nu

Gẹgẹbi ọrọ ti a fi ṣe ori ọrọ olotu wa ninu ọsẹ ti o kọja nipa eto ilera tuntun ti Minis ta alamojuto eto ilera gbogbo ilẹ Nigeria, Dokita Moses Adekoye Majẹkodunmi, gbe jade fun anfani awọn ara ilu Eko ti a ni ki awọn ara wa gba lati dan eto ilera na wo nitoripe ko buruju loju awa oniwe irohin Eletı-Ọfẹ, Ọrọ eto ilera na ni a tun pada si lọsẹ yi.

Awon oṣelu wa ti a ran lọ si ile Igbimọ aṣofin gẹgẹbi aṣoju ti ni ki nwọn fa iwe eto ilera na ya, awọn ko fẹẹ rara. Bi ẹta inu ni nwọn fi ṣe eyi, bi fun anfani awa ti a ran wọn lọ gẹgẹbi aṣoju wa ni gbogbo rẹ fẹre ye wa na, ṣugbọn nkankan ni a fẹ ki ẹnyin ọkawe wa ni igun mẹrẹrin ilẹ Nigeria mọ daju–awọn ara ilu Eko ju nkan atata nu nipa eto ilera tuntun na ti nwọn ko jẹki a dan wo.

### Esin Ota ...

Awọn Yoruba ni ẹṣin ọta ẹni ki ga loju ẹni; bi o ti wu ki ẹṣin na ga to, ko ga nu ni a o kaa si. Iyẹn ni ọrọ ti Dokita Majẹkodunmi, Minisita alamojuto eto ilera ti o daba lati tun ori awọn ara Eko ṣe fun wọn.

Ko si nkankan ti o faa ti awọn oṣelu yi fi kọ "ỌMỌ TUNTUN" na si Majẹkodunmi lọwọ ju wipe ko nṣe ara wọn lo. A gbọ ti ọpọlọpọ ninu awọn oṣelu yi nso wipe ọna ẹburu ni Ọgbẹni Majẹkodunmi yi fi gba di oṣelu nitorina awọn ko le fọwọ si abakaba ti o ba gbe wa si ile igbimọ nitoripe on nikan ni yio gba iyi ibẹ.

### Ki Ga

Ti o ba jẹ wipe Ọgbẹni Majẹkodunmi jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni tabi ọmọ ẹgbẹ Ọlọmi (NPC) ki o to gbe ỌMỌ TUNTUN na jade ni nwọn ko ba si kii ku ewu ni ile igbimọ awọn asofin na, ko ba di ọla ki ọmọ na fo saulẹ ki o ku bamu bamu.

Awa ko kọ ọrọ iyanju wa ti ọsẹ yi lati fi bu ẹnikan tabi lati fi yin ẹnikan awọn oloye ti o ba ṣẹ ku ni ilu Eko ni a mba wi nitoripe Eko ti di Eko–ila nisisiyi ọkanjuwa owo ni o nda olukuluku wa lamu. Otitọ ko si ninu aiye mọ. owo lo ku ti olukuluku nle pa. Bi ko ba nṣe bẹni kilo di awọn ara Eko lẹnu ti nwọn ko fi le sọrọ rara lori eto ilera tuntun na? Ṣebi ẹniti o ba wọ wipe ẹ nfi itọju atata gba tọmọ tọmọ, taya taya ninu ile iwosan (hospital) l'Eko?

Abọ ọrọ ni a nsọ f'ọmọluwabi.... sugbọn awa mọ wipe awọn ara Eko ju nkan atata nu, adura wa ni pe ki Ọlọrun ki o fun wa ni alanu miran ti yio tun gbe eto yi dide fun wa.

# Iwe Si Olotu

## OkparaSo Yi Tan !

Ọrọ ti a gbọ laipẹ yi ni wipe Dokita Okpara tiṣe olori awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni o da a ni imọran wipe ki gbogbo awọn alakoso Ijọba ilẹ Nigeria fọwọ si ofin ti awọn yio ma fi mu awọn oṣelu ọta awọn lọ fi pamọ si iyara ti nwọn ti kọ si isalẹ ilẹ.

O ya mi lẹnu wipe a le gbọ iru imọran bayi lẹnu Dokita Okpara tiṣe Olotu Ijọba Ipinlẹ Ila Orun. Iyẹn ni wipe bi enia ko ba sun mọ enia ko ni mọ bi o ti ri ?

Tabi Okpara alara paapa ko mọ wipe nkan tun le yipada, ki nwọn si lo ofin itimọle alajale na fun on na ni ọla. Ẹda ti o ba gbin-ika ni ọrọ na, ọmọ rẹ a jẹ nibẹ.

Emi ni,
E. Laitan

Ibara,
Abẹokuta.

# A Nfe Ilosiwaju Ni Oferese

Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba, mi laye lati kesi awọn alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa lati bawa mojuto ilu Ọfarese nitoripe ilu na ko si ninu awọn ilu ti o kereju, awọn ara ilu na ko si nfi owo-ori wọn jafara rara.

A fẹ ki nwọn ba wa tọ ju ọna moto wa nitoripe lati igbati ojo ti de yi oju ọna na kọṣe gba rara, bẹ ko yẹ ki ilu wa ko mọ ni ọna

Ekeji, awa ara ilu na ni a ṣe gada afara funra wa, a ko si ni ile-ẹkọ (school) lọdọ wa. A bẹ wọn ki nwọn jọwọ ki, nwọn wa kọ ile iwe fun awọn ọmọ wa, ki nwọn si tun wa fun wa ni omi ẹrọ.

Olotu, mo dupẹ lọwọ yin fun aye ti ẹ gba mi

Emi ni
S. A Saka Adigun

Opopo Moloney
Eko

# Isemo Ko Dara

O yẹ ki adupẹ ẹnyin Olotu iwe irohin ilẹ Nigeria jake-jado ti ẹ tete lọgun too sita ofin buruku ti awọn alamojuto iṣẹ Ijọba wa fẹ gbe bọwa lọrun ti oya ọpọlọpọ awọn ẹlomiran ti ko ṣẹ ti ko ro ni nwọn ko ba ti ma ṣe iwe lati lọ fi nwọn pamọ saja ilẹ nisisiyi.

Mo ṣebi awọn oṣelu wa ni ilẹ Nigeria ni nwọn fi igbakan bu ẹtẹ lu awọn oṣelu Ghana nitori ija-ilẹ ti nwọn kọ awọn Aganyin lọ ti ko si si ifọkanbalẹ nilu wọn. mọ!

Kini o tun ba awa na de ibi irokuro yi ? Boya afarawe ni, sugbọn ẹni-Ọlọrun ni Ọlọla Tafawa Balewa tiṣe alakoso gbogbo wa gba, A bẹ ẹ, ki o jọwọ, ki o ma ba wọn lọwọ si ofin buruku yi o,

Emi ni,
Baba Isalẹ

Ebute Metta

# Eleti-Ofe D'araba

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

### Alabi Alalo

Mo mọ wipe gbogbo enyin ti e ma ... si ... ọsọsẹ lati gbọ alọ ati itan lẹnu Ọgbẹni Alabi ninu ẹrọ asọrọ-m...gbesi (redio) Ibadan ni yio ... lẹnu lati gbọ wipe ọgbẹni na jalaisi ni ijarun ninu ile awọn oniwosan Ibadan. Iyawo meji ni Ologbe na ni, awọn si bi ọmọ jahurata fun un. BABA 'EMI, MỌ O'! ọrun re.

### Oshemawe Alaga

Emi Ayiluka ba Alaiyeluwa Ọba Tẹwọgboye Keji, Oshemawẹ ilu Ondo ...ọ nitoripe mo gbọ wipe on ni agba kan lati ma ṣe alaga awọn ijoye ati awọn lọbalọba ninu ile ipade igbimọ wọn ni Agodi. Mo ba Ọba na yọ pẹlu gbogbo awọn ọmọ Ondo, ṣugbọn lọjọ wo ni ao ṣe ajọyọ oye alaga na?

Ẹ ma gbagbe wipe emi Ayiluka mọ ẹmu mu dọgba pẹlu ẹran ẸGI, ṣugbọn ẹran okete ni mo mọ jẹ rara. Ju gbogbo rẹ lọ ẹ sa jẹ ki nmọ ọjọ ajọyọ na ni ilu Ondo.

### Asofin Olowo

Ni ijarun awọn aṣofin wa tu itọ si ara wọn loju daradara ninu ile igbimọ ti nwọn ti nṣe ipade lori ọrọ owo-irinsẹ (travelling allowance) ti nwọn sọ wipe awọn fẹ ki Ijọba bu sowo na fun awọn ...iye ti di aiye jẹun jẹun. Bi awọn oṣelu kan ti ntako aba na wipe awọn kan nṣe kobẹkubẹ lọ gba owo irinsẹ lọdọ akọwe asinwo ile igbimọ aṣofin na.

### Eto Ilera Eko

Dokita Majẹkodunmi ṣe gud gudu meje fun awọn ara Eko nipa ọrọ eto ilewosan ti o fẹ gbe jade fun wọn ti awọn kan ṣe e ni kaka ke'ku majẹ seso a fi ṣe awadanu. Nwọn ni Adekoyejọ kiṣe ara awọn bawo ni o ṣe ma da'ru ti awọn yio ma gbe e?

Nitotọ Adekoye ko nṣe oṣelu ti o wa ninu ẹgbẹ kan, ṣugbọn oṣelu ti o wa ire awọnu ara ilu nṣe.

Emi Ayiluka ṣe akiyesi wire awọn ỌMỌ EKO ko sọrọ nilu mọ, awọn ARA Eko ni o ku ti nwọn nsọrọ fun wọn lori ọrọ ilu ,eyi ara!

Ti mo ba purọ ṣe ẹnyin na ... bi ọrọ ti nlọ si nilu Eko nisisiyi? Awọn Kansilọ ti e yan si ile igbimọ ibilẹ Eko (Town Council) ko ni en... ninu ọrọ ilu na tobe mo a fi ti nwọn ba le lọ bẹ Minisita alamojuto Eko. Ọrọ re o!

### Gbadebo Keji

Boya enyin ọkawe mi niran ọrọ kan ti mo ji sọ fun yin ninu oṣu ọdun titun (January) ni iwọn nkan bi oṣu kejọ wipe Ọmọba kan mbẹ ... ...o'nta ti a npe orukọ rẹ ni SAG, on ni awa od... ...ọ...uta nfẹ fi jẹ Ọba Alake titu i dipo Ologbe Lada...ọ.

Ọrọ na i na ṣẹ, mo dupẹ! Ọmọ Ọba Samuel Adeshina Gbadebọ ti d'ọba. Nko gbodọ pe ni SAG oruko nagiję ti a ma npe ara wa mọ, a fi ki ...fi idobale ge e, ki nma wipe KABIYESI ỌBA ALAKE GBADEBỌ KEJI. Emi Ayiluka mbọ wa ki ọ ni Ipebi l'Ake laipẹ yi o. Kabiyesi!

### Abẹokuta Dun Gba

Gbogbo awọn ero ti nwọn gba ọna Abẹokuta lọ si Ibadan ninu ọsẹ ti o kọja yi ni nwọn kan saara si awọn Oyi b... ti ... la ... ọna mọto ti o ti bẹrẹ lati Eko ti o fi de Abẹokuta ati Ibadan. Ẹgbẹgbẹrun moto akẹru ati mọtọ ayọkẹlẹ ni o gba ibẹ ni ọsẹ ti o kọja yi nigbati odo MAJIDUN lọna Ikorodu binu, t... o lẹ gbẹbọ.

Emi Ayiluka paapa jẹri si ọna-titi Abẹokuta pe ko nṣe oju ọna ti a fi pajasiri ṣe, nitoripe ọna na jinna diẹ si Ibadan ni ko ... ajẹ ki awọn Onimọto Kia--Kia gba ibẹ.

### Orisa Majidun

Sugbọn o da mi loju wipe ẹgbẹgbẹrun awọn enia ti o nlọ si Ibadan loni lati lọ wo ija ẹiẹṣẹ ti Tiger ati Fullmer fẹ ja ni nwọn yio gba ọna Abẹokuta nitori orisa Majidun ti o wa lọna Ikorodu nisisiyi. Otitọ ni emi Ayiluka nsọ fun yin o.

### Owo Ile Di Goboyi Ni Benni

Enyin ọrẹ mi nkan miran wọlu awọn ẸDO ni Benni City lori awọn akọwe Ijọba gbogbo ti nwọn nyi nipo pada lọ si Ipinlẹ agbedemeji Iwọ orun ti nwọn ṣeṣẹ da silẹ. Ilu Benni ni nwọn fẹ fi ṣe olori nitorina awọn ara ilu na ti bu owo gọbọyi si owo iyara kọkan ti nwọn nfi haya.

Mo gbọ wipe ọpọlọpọ awọn ọmọ Ilu Binni ni o nlọ ko MALẸ nisisiyi lati le te e kọle mehaya f... awọn akowe ti isẹ ngbe bọwa si ilu wọn. Ṣe ẹnyin na wa ri wipe tọbọ ye ọbọ ? Awọn ti o ni ki nwọn di ipinlẹ agbedemeji Iwọ-orun siiẹ ye ...ọn; nkan ti ọbọ yio jẹ ni ọbọ nwa.

### Wayo D...!

Ere-bolu afẹsẹ... de ! nwọn ONIWAYO berẹ is. B... enyin ọkawe mi le sọ wi, e kinni ... ...uka ri nipa ọrọ idije pulu (footb...) ti e nko owo lelori nilẹ Nige... ọsọsẹ.

(Wo yoku loju ewe keji)



# Alaye Ilera

( O bẹrẹ loju ewe kẹta )

## Anfani Wa

Ni kete ti eto ilera yi ba ti bẹrẹsi ṣiṣẹ, gbogbo awọn enia ti nwọn ba ngbe ilu Eko ti nwọn si ti san ebu owo ti o yẹ ki nwọn san, ni nwọn yio bẹrẹsi jẹ anfani afikun gbogbo iṣẹ ilera ati itọju awọn alaisan ti eto na yio mu lọwọ. Awọn aboyun yio jẹ anfani itọju ọfẹ, ninu oyun ita lẹhin ti nwọn ba ti bi ọmọ wọn tan, ni awọn ilẹ-iwosan kekere ti Ijọba ba ti da silẹ ni adugbo enikokan wọn, lati ọwọ dokita ati olutọju alaisan ti nwọn mọ iṣẹ wọn bi igba ti enia mọ owo. Ọfẹ ni nwọn yio gbẹbi fun awọn aboyun ni awọn ile iwosan na pẹlu.

## Fun Omode

Nibikibi ti o ba ti ṣiṣẹ, eto yio wa fun dokita ati awọn olubojuto alaisan lati bẹ awọn aboyun wo ninu ile wọn fun itọju. Nwọn yio si tun fun awọn aboyun bẹ ni imọran nipa ọrọ ohun jijẹ, imọtoto ati awọn ogun ti o yẹ ki nwọn ma lo lati ba le aisan jina.

Bakana, eto ilera titun yi pese aye pataki fun itọju awọn ọmọde ati fun isara fun arun. Gbogbo awọn ọmọde kekeke ni ilu Eko ni awọn 'dokita' yio ma ṣe iyẹwy ni ak ko de akoko. Awọn ọmọ ti ayẹwo yi ba si fihan pe ara wọn ko da yio gba itọju ni ile iwosan ti o ba wa ni adugbo wọn. Ọfẹ si ni gbogbo awọn itọju ti a o ba fun awọn alaisan ni ile iṣẹ ilera ti adugbo kọkan, tabi ile-iwosan ti o ti wa l'Eko ṣaju eto titun yi, tabi ni awọn ile-iwosan miran fun abami arun labi fun gbogbo ogun ti a o ba lo lati fi le arun sẹhin.

Ẹnikẹni ti o ba ti san ẹbu owo tirẹ labẹ eto yi ko tun ni san owo kankan mọ fun gbogbo itọju ti yio ba gba ni ile-iwosan eyiowu ki o le jẹ ni Eko, bi o ti wu ki aisan na le pọ to, tabi ki itoju na le falẹ to. Ṣugbọn sa o, awọn enia fun'ra wọn ni yio san owo awo oju, tabi ẹhin agbelẹrọ tabi igi agbeẹrọ ti a bi ko si wọn ni paa tabi ọsẹ.

(koi ti pari)

# Baba Alarina Aunti 'Koforun Parare Oro Buse

LONDON —Boya ẹnyin ọkawe wa miran irohin nla ... ti akọwe onirohin wa fi ranṣẹ si wa lati ilu oyinbo ni ibẹrẹ oṣu ti o pari nipa awọn ọdọmọdebinrin aunti "Koforun" meji, Christine Keeler ati Maady Rice-Davies ti awọn ọlọpa ni Dokita Ward nfi ṣe iṣẹ ajẹyo, o nko wọn fun awọn ọkunrin ti nwọn mba wọn lo ninu iyara rẹ.

Dokita Ward na ti jẹ ki ta na sun lori wipe o majele ni ọjọ ti nwọn nfi awọn ọdọmọdebinrin fẹ lọ ojọ fun un, o si ṣe iṣẹ panṣaga, ti i... asi ni ile awọn alai... ni arin ilu London ni ijẹjọ. Ẹsun mẹ... awọn ọlọpa fi do-

Ọjọ mẹjọ gbako ni awọn fi ro ẹjọ na niwaju ogunna gbongbo adajọ Kotu Old Baily, gbogbo dokita na ni nwọn wa jẹri awọn aunti koforun ti nṣe ọmọbinrin kan ti awọn enia ba lo ninu ile awọn se oyun fun.

# E Ka Irohin Ayiluka Losose ni oju ewe karun

# Ere Bolu Afesegba Bere



Ere bolu afesegba ti awon Oyinbo ma ngba ni akoko erun lodo won fe bere ninu ose yi; osu meta gbako ni awon ti o ngba bolu na fi lo se isinmi ki nwon to tun pade si ibi ise won. Aworan yi ni awon omo egbe onibolu na kan ngba ti nwon.

# Nigrians Gain Practical Refinery Experience In Britain

LONDON—Three Nigerians are among 130 under-graduates getting practical refinery experience under the British Petroleum Company's vacation training scheme this years.

They are J. C. Okoli, of Udi, a first year chemical engineering studend at Loughborough Technical College; J. M. Omole of Ilesha, a first yeay chemical engineering student at the Royal College of Science and Technologry, Glasgow; aud A E E Ejaife of Ugbelli, who has Completed his first year in mechanical engineering at Battersea Technical College, London.

The three are spending eight weeks of their long vacation at Llandarcy Refinery in South Wales wher they will get a workshop grounding in the production of basic refinery fittings.

Out of the 130 students given this chance of practical training, eight come from developing countries and seventy are aking full-time degree ctourses sponsored by B P.

## Eastern Region Official Studies London Money Market

LONDON—Mr J.U. Obidegu, Assistant Secretary Ministry of Commerce, Eastern Region has begun a vear's study of investment procedures in the London money market

'It is hoped that my studies will provide much valuable information required by my Government for our own investment programme", he told Our correspondent this weekend.

Mr. Obidegwu arrive in London two mo-ths ago and spent his first month with the Finnance Department of the Crown Agents. He is now observing the work of a leading firm of Brokers.

"I shall be going through all the departments of the firm, covering investments new share issues, transfers and so on", he he explained.

## "Hamlet" To Launch Britain's National Theatre

LONDON—Britain's National Theatre will be launched on 22nd October with a performance of "Hamlet" at the Tneatre's temporara home, the Old Vic. A permanent theatre is to be built on London's South Bank.

Sir Laurence Olivier, Artistic Director of the new Theatre announced yesterday that it was their intention to build up rapidly a large repertoire of both classical and modern plays from many countries.

He said the company would be a permanent group, with guest artists appearing from time to time. 'I will be an international theatre in the truest sense,' he added.

The nature of the Theatre's policy is evident from the choice of the first seven plays to be produced. Two are by Shakespeare, one by Max Frisch, and another by Sophocles. Contemporary British plays will also be performed.

## BritishShip-yarnTo Build To Supertankers

LONDON— Two 63,000 ton supertankers have been ordered by Shell Tankers Ltd., London, from a yard in north east England, it was announced yesterday.

The firm, Joseph L. Thompson and Sons, of Sunderland, who are currently building an 80,000 ton tanker for the Norwegian Owners Fred Olsen and Co., Oslo, will deliver the new ships in 1965-6.

The vessels will be over 760 feet long and powered by diesel engines giving a service speed of about sixteen knots. The keels will be laid next year.

BE TALLER

Increase your Height. Details free. Add:— C.T. Hospital, Azad Market,

Delhi 6, India.

## Princess Anne Becomes Pupil Of Benenden School

Princess Anne, who celebrates her 13th birthday on August 15, is to go to Benenden School in Kent, England, at the beginning of the autumn term this year. She thus follows the new Royal pattern set by her brother Prince Charles the Prince of Wales who is now at Gordonstoun School in Scotland. Previously, all children of the British Royal Family have been educated privately.



# Ayiluka Ni:

## Wayo De!

(O bere loju ewe karun)

Awon kan wa, osose ni nwon npa owo apasapo ninu owo ti e ba da fun won, gbogbo won ni mo mbo wa ko jade bi omo ojo mejo.

## Awon Omo Eko

Mo gbo wipe gbogbo awon omo Eko ti o mbe ni Ibadan fe dabira fun Oba Adele ati Oloye Modupe Johnson (JMJ) nibi ariya kan ti nwon fe se fun won ti nwon ba ti gunle nibi iran ese-jija ti nwon mbo wa wo loni. Ogbeni Jawando ati Pa Falase pelu gbogbo egbe awon omo Eko, emi Ayiluka ki y'n, e ku kukari.








*Start comparing machines and you'll find yourself owning a*

**HONDA**

- The machines with automatic clutch, electric starter trafficators and a score of extras.
- The machines with 4-stroke engines. Use petrol ONLY. NO petrol and oil mixture!
- The machines which are built to last

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, (E.B.), IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT & ABA


## Oloye Kan Da Aso Ewon Funra Re

EKO—Lojojumo ni nkan orisirisi nsele ni ilu Eko, eyiti a ri ni ijete ojo Alamisi ni ti Oloye kan lati Ago Iwoye ni Ijebu ti o da aso ewon fun ara re, oruko oloye na nje Akin Oguntoye.

Nigbati onirohin wa bi Oloye Oguntoye lere wipe kini o ba debi a nwo aso ewon kiri ilu Eko lati Ijebu wa, o ni oun nfi ba olori awon, Oloye Awolowo, ti o wa ni ihamo logba ewon kedun ni. O ni olori awon ko le ma jiya lewon ki awon ma wo agbada funfun kiri.

Nitoto o to ogun enia ti nwon wo aso ewon wa si Kotu-garan ni odun lana nigbati awon kan nparo kiri wipe adajo ti se idajo, nwon si ti da Oloye Awolowo sile.

## Awon Janduku Ilu Eko Nfi Oruko Awolowo Jeja

EKO — Gbogbo awon oloja ni won ko igba oja won wole ti awon oyinbo onisowo si sare ti ilekun ile oja won ni ojo Alaruba ti o koja lo yi, nigbati won gburo wipe awon janduku kan lati awon agbegbe ilu Eko ti wo ilu lati se jamba fun awon onisowo ni oruko Awolowo. Ohun ti o fa sababi yi wa ni wipe awon opuro aiye kan so wipe ni ojo na ni Adajo da ejo ti Ijoba mba Oloye Awolowo ati awon omo ehin re Ogun se, ejo yi ti wa ni ile ni nkan bi osu meje sehin.

# Ijoba Ghana Mba Minisita Won Sejo

ACCRA — Awon olopa ilu Ghana ko meji ninu awon minisita won atijo lo si iwaju adajo kotu pataki kan ni owuro ana pelu esun wipe nwon dite si Ijoba. Oruko awon minisita meji na ni Ako Adjei, minisita alamojuto eto okere, Tawai Adamafio, minisita alamojuto ikede Ijoba pelu awon meta kan, H H Cofie Grabbe, akowe egbe oselu C P P., Robert Berjamin Otchere ati Joseph Yaw Manu.

Lati bi odun kan ni awon alakoso Ijoba Ghana na ti ti awon odaran na mole pelu iwe ofin ma duro sejo; ofin na fun ijoba ni agbara lati ha enia mole fun odun marun gbako lai gbo tenu re.

Esun ejo ti nwon fe ba won ro ni wipe nwon dite si Ijoba, nwon fe pa Olotu Ijoba ilu won, Dokita Nkrumah lojo ti o rin irin ajo lo si Kulungugu ni ilu Oke Ghana ti nwon ju bombu si i sugbon awon enia miran ni bombu na pa.

Enikeni ti o ba jebi iru esun ejo ti nwon mba won ro yi pipa ni nwon ni lati pa won a fi ti Dokita Nkrumah paapa ba darijin in:

Awon adajo meji, Ogbeni S. Adoo ati Van Lere ni won yio joko pelu adajo-agba Olola Arku Korsah ni nwon yio joko sejo na.


AKIYESI

**Enyin Okawe Irohin Eleti-Ofe Ao le Irohin DICK TIGER**


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos, Box 467 Phone 23370; Editor: (Olotu) Ola. Onatade, 15 Kosoko Street, Lagos